JAMBA S'OLE OLOHUN KIGBE L'OJA JANKARA




# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO




VOL. X No. 558. ELETI-OFE LAGOS, SATURDAY, FEBRUARY 8, 1958. KOBO MEJI (2d)

## Jamba S'ole, Olohun Kigbe

EKO. Omo jaguda kan ti o atu owo jo lati fi da ara iyawo re owo na je Pons marun, lo fi owo na pamo si arin awon ogbogi ti nwon nta ni oja Jankara ni Idumagbo.

Owo na ti wa ni ipamo to osu meji, Johnson omo jaguda yi, a ma lo wo owo yi nibiti o fi pamo si ni alale.

Omo Jaguda miran ti o nje Sam-de-Boma, a ko mo bi o ti se de ibiti owo yi wa, o gbe £5 na o si sare lo ba Johnson pe ki o wa gba dani, owo oo ba nkan.

Ni Sam-de-Boma ati Johnson ba salo si Ebute-gbeti, nwon si pin owo na nwon si bere si na al inakuna. Nigbati ile su Sam si lere na owo tire tan ti Johnson ku sile mewa.

Nigbati ile su, Johnson lo ye owo tire wo nigbati o de ibe ti o ri gbogbo ile ti o daru o fi owo mu ori, nigbati owo afere lowo Sam lo ti so fun Johnson pe owo ti o ku lowo on ni on yio fi woko lo si Abeokuta lojo o s tabi Johnson yio ba on lo?

Johnson dahun pe on ko lo o lo ibesi to-o nigbati ko ri owo re mo-Gbogbo awon olugbe re mbi lere, kini ohun ti o se e? nse lo deke ti ko le fohun.

Nigbati o reti ki Sam-de-Boma pada de ti ko si de lo ba wa lo si Abeokuta ese samo-samo awon ti nsa ni Abeokuta ni awon olopa ba ki i awon gbe ja dau ewon.

Nisu ewon yi lo wa le ri Sam-Boma ti o joko ni bi iyawo. Eo ri, okun ko dara lorun, iwo je fe e.

## Ipade Igbimo Nla Nilu Eko

EKO. Ipade Igbimo 'bere nilu Eko (House of Representative) ni Ojo Atalata (Tuesday) lati se arero alba soki ki asiko ti igbimo yio pade pataki to to.



SIR JAMES ROBERTSON

Die ninu awon ti a le dauko ti o wa sile igbimo na ni Gomina agba ti o si ipade na Gomina Iwo-Orun Oke Oya, ti Ila-Orun, Alhaji Tafawa Balewa Oloye Obafemi Awolowo Akintola Adelabu ese awon Oniwe Irohin pe sibe pelu. Gomina agba ni o soro ki awon Oniwe Irohin to jide.

## Gesi Mba Ajeji K'egbe



Awon enia merin ti a nwo ni iduro [illegible] ni awon ajeji enia ti awon Gesi gba [illegible] won. (Edinburgh Club House).

Oruko awon ajeji na ni wonyi, lati [illegible] ni apa otun, Sinabu Seth, ara ile [illegible]. Khalil Maastry ara ile Lebanoni. Lele [illegible] ati Asta Halldors ara ile Iceland. Awon ajeji enia ti o wa ninu egbe yi le ni ogota.

Larin won, ko si edekoyede wipe emi ni Gesi, emi ni Faranse tabi emi ni enia dudu. "Oko ni oloti ni Aganyia, gbogbo wa lo jijo agbo [illegible]". Owe ni.

# LAGOS RACE CLUB
## SPRING MEETING
### Saturday 15th, Saturday 22nd Feb, And Saturday 1st March 1958.

| FIRST DAY | | START |
|---|---|---|
| RACE No. 1 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 2, 45 p.m |
| RACE No. 2 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 3, 15p.m |
| RACE No. 3 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 3, 45 p.m |
| RACE No. 4 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 4, 15 p.m |
| RACE No. 5 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 4,45 p.m. |
| RACE No. 6 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 5,15 p.m |
| RACE No. 7 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 5,45 p.m |
| RACE No. 8 | Five Furlongs Handicap Top Division | 6, 15 p.m |

| SECOND DAY | | |
|---|---|---|
| RACE No. 1 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 2. 45 p.m. |
| RACE No. 2 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 15. p.m. |
| RACE No. 3 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 45 p.m. |
| RACE No. 4 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4. 15 p.m. |
| RACE No. 5 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No. 6 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 5. 15 p.m. |
| RACE No. 7 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 5, 45 p.m. |
| RACE No. 8 | Seven Furlongs Handicap Top Division | 6. 15 p.m. |

| THIRD DAY | | |
|---|---|---|
| RACE No. 1 | Ten Furlongs Handicap Bottom Division | 2. 45 p.m. |
| RACE No. 2 | Ten Furlongs Handicap Bottom Division | 3, 15 p.m. |
| RACE No. 3 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 3. 45 p.m. |
| RACE No. 4 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4, 15 p.m. |
| RACE No. 5 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4, 45 p.m. |
| RACE No. 6 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 5, 15 p.m. |
| RACE No. 7 | Polo Scurry | 5, 45 p.m. |
| RACE No. 8 | Ten Furlongs Handicap Top Division | 6.15 p.m. |

## U. A. C. Recent Promotion

Mr E. O. Anenmeka (Enugu); Mr P. I. Jegbefume (Onitsha); Mr J. T. W. Pepple (Umuahia), and Mr J. A. Umoh (Port-Harcourt), have all been promoted to Management Status with effect from the 1st of January, 1958.

Mr E. O. Anenmeka, who comes from Asaba, was educated at St. Mary's School at Port Harcourt and after leaving school became a Teacher until he joined U. A. C. as a Clerk in the Produce Department at Calabar on the 1st of April, 1951. After working for two years in the Hardware Department, he was promoted Grade Two Sales Assistant. On the 1st of January, 1956 he was promoted Grade One Sales Assistant at Ilu and a year later was transferred to Enugu where he is still employed.

Mr P. I. Jegbefume comes from Abavo Town and was educated at Abavo Sapele Catholic School. He also worked for six months as a School Teacher before joining the Company as a Junior Clerk in the General Goods Department at Warri on the 1st September 1943, in 1954, he was promoted Grade Three Provisions Wholesale Storekeeper, and two years later Sales Assistant in Grade Two. After working for just over a year in the Merchandise Department at Sapele, he was transferred to Onitsha and promoted Sale Assistant for Drugs and Perfumery in Grade One, where he is still working.

Mr J. T. W. Pepple comes from Bonny and was educated at Bonny Government School. On leaving school, he joined the U. A. C. as a Beach Clerk in 1936. He has been a Senior Beach Master at Umuahia for a number of years being promoted to Grade Two in 1953 Grade One in 1956 and Senior Clerical on the 1st of January, 1957. Mr Pepple is still employed at Umuahia.

Mr J. A. Umoh was born at Afaha Iman and was educated at Etinan Institute, Uyo, subsequently working as a Teacher with the Qua Iboe Mission until he joined the Company in 1939 as a Beach Clerk. On the 1st of January, 1953, Mr Umoh was promoted a Storekeeper and reached Grade Two on the 1st of January, 1954, in the Textiles Department at Calabar. The following year he was appointed a Sales Assistant in the Haberdashery Department in Port Harcourt and became Grade One Clerk in charge in 1955, being promoted to Senior Clerical Grade last year.

## Alafin Ana Tilu Oyo



Eniti a nwo aworan yi ni Alhaji Adeyemi Keji ti o nse Alafin ana nilu Oyo.

Awon ajatilehin rẹ ti gbero lati mu oran re wa siwaju Oluwadi oro (Willink Commission of Inquiry) nile Oyo. Sugbon Oluwadi na taku wipe, on ko fẹ lati gbọ oro re ni tori on ko wa lati tako ohun ti Ijoba ti ṣe, beni oro Alafin yi di ohun agbeti ti ko lori, ti ko nidi bi eje osun.

## Ole Ko Aladura L'eru Lo.

Ọmọba kan ti baba rẹ ni owo lọwọ, ti on kanna si jẹ Aladura, nigba gbogbo ni ọmọba na ma nsọ asotẹlẹ fun awọn enia, ti awọn si ma mba bọ.

Laipẹ yi ni ọmọba na lọ si ọja lati ra aka sile ti yio fi ṣe awọn alejo kan ti o mbọ wa sile wa ba wọn ni alejo.

Bi o ti nraja lọwọ bẹni emi bale, awọn si nsọ fun wipe, ki o tete pada sile.

Kaka ki o gbọ, nṣe lo ṣe eti kunkun, ẹmi mimọ nsọ fun lemọlemọ wipe ki o dehin sile; sibẹ ko pada o si mba ọja rira rẹ nlọ.

Nigbati o raja pari tan lo to pada sile, nigbati o pada wọ inu yara rẹ lọ nṣe lo bu gbaragada si ekun, o wipe. awọn ole fọ windo on nwọn gba ibẹ wọle, gbogbo awọn ohun iṣura on ni awọn ko lọ, yẹ?

Ibẹ ni obinrin Aladura kan sọ bayi pe, mo gbọ ohun ti o sọ bayi pe igbonran san ju ẹbọ lọ ifeti sile san ju ọra agutan lọ.

Ọmọ na si dahun p... bẹni mo tuba Oluwa. e.




## Ofin Moto Si Ile Dahomi Ati Nigeria

Ninu Iwe Gazette No 3, Vol 45, Government notice No 64, ti [illegible] jumo papo ge ofin yi ni ojo 9th osu Jan. 1958 wipe :-

1. Enikeni ti o ba fe gba ile Dahomi koja tabi ti o fe lo sile Dahomi ni lati gba iwe ase (Passport) lati rin irin ajo.

2. Eniti o ba ni iwe ise lowo, sugbon ti oluware fe ya ni Ajase Kutonu tabi ilu miran ti o wa labe Dahomi ni lati gba iwe lodo Asoju Faranse ti o wa nilu Eko. Sugbon a ko ni bere iwe kan lodo awon ti o ba niwe ase lati rin irin ajo.

3. Gbogbo moto ti ko ba gba nomba (License) titun yio ni ijogbon tabi ki moto na ati stuke re ni iwe International Certificate.

4. Gbogbo moto ti yio ba gba ile Dahomi koja ni lati wa labe Insurance.

5. Gbogbo moto ni lati duro ni Bode fun ayewo awon Osimoto.

A se ofin yi dipo eyiti a koko se ninu Govt. Notice No. 271 of 1946.

## Itan Awon Ogboju Ode Loke Amilala - Amilolo

(APA III)

Nigbati awon Ogboju Ode na wo igboro ilu Alo, nwon bere si sunjala. Ll akoko, nwon ko ri enikan nigbana ni Jagilegbo-Sogun Ode Ibadan da orin bayi wipe:-

Erin goke o,
Erin goke o se
Agunfon Erin goke Alo

Nigbati awon ode na dario bayi, gbogbo won gberin na, gbogbo igi igbo lo go'erin yi ti gbogbo re gbojikan ti o si aho gee.

Ofin awon ode ni wipe, nwon ko gbodo tafa tabi ki nwon ta akatampe ni Oke Amilala - Amilolo, gbogbo ohun ti o ba ri si ki o fi ja.

Ogunfunmi-alre lo koko gboju soke, ti o ri awon agbo Efon, ti nwon nfi iwo lu iwo bowa, lese-kanna ni gbogbo ini igbo darin bayi pe:-

Ode pade ode,
Ologini ko Ekun losa.
Ode pade ode.

Ogbori Odo-ja - bi -oji si adu oje kan, o si kase kan ro Ojo ola kan su regede efufu bere si damu igbo, ara nsan, mone - mono nko yeri. Awon Efon ko feran iru nkan bawonyi, kiakia ni nwon pora. Ojo na si fo o.

Awon Ogboju ode na mba irin ajo won lo sile oba ilu Alo. Bi awon ti nlo, beni awon ngbo bayi pe Kanko, kanko - kanko kanko. Nigbana ni Kanko - kanko ogboju ode Oado dahun pe tani npe emi Kanko - kanko? beni Okere kan jabo sile lati ori igi, o wi fun Kanko-kanko pe ore ti o se fun on nijosi ti o ko jeki eiye Idi pa on lomo je on yio san fun o loni.

O ni nigbati nwon ba dele oba nwon ko ni ri enikan ba soro sugbon bi nwon ba de agbala kini ki nwon gbe edun kan beni ni ekeji ati eketa nigbati nwon ba de ekerin nwon o ri imi Osumare eniti ko ba ni ise oro ki o mase fowo kan nitori o mbunije. Lose to mbo a o so ija awon ogboju ode ati awon Inaki nilu Alo.

## Kilo Pa Awon Enia Nwonyi

GLASGOW A gbo iro-hin wipe, awon enia meta ku sinu moto, yala nwon pa ara won ni, tabi enikan lo pa won ni a ko mo nitori a ko ri eniti o ri won.

Bi oro na ti lo niyi:- Ni owuro ojo Sunday kan ti gbogbo enia nkoja lo si sosi legbe kan oju ona ni awon enia ri ti awon enia meta ku sinu moto kan ti o je pa ori ni awon tita won ni nibon.

Eniti o ku sidi ibiti awon nwa moto ni John Hailey omo odun marundilogoji obinrin ti o ku si egbe re ni Joyce Melkle eyiti o ku si ehin moto ni omode kekere kan ti o nje James Wand ti ko ju omo odun mokandilogun lo, awon si ba ibon ilawo (Revolver) nibi ese omo na.

Kayefi ni oro yi je fun awon olopa, nitori enikan ko gburo ibon, ko si eniti o ri won nigbati nkan yi sele. Nwon si nwadi oro na lowo.

## Kere o!

A ti ni origirigi ogun German to sese de [illegible] onirunru nisan [illegible] tobinrin. Tete wa [illegible] k'o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos

# ELETI OFE

A-NIU-WON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

23, Kosoko Street, Lagos "ELETI - OFE LAGOS"

P.O. Box 467 Phone 23379

VOL. X. NO. 518 LAGOS, SATURDAY FEB. 8 1958


## Bojn Wo Ehin. Wo Ohun Ti o Ti Koja

Akoko oro oke wosika wa yi ni a fi se esin oro wa. Ose yi lati fi gba enyin okawe wa ni iyanju lati Igbesi aiye omo enia l'ode aiye rere yi.

Ise ore mi, boju wo ehin, wo ona wo, ki o to sure koja. Bojuwo opolopo awon odun ti o ti je koja, tun bojuwo akoko ti o njogba, lasiko ti aiye mbe lowo re ohun ti o nri ti inu re ndun ni ki o ro, maṣe ro ti ohun ti o mbe o ninu je. Tun bojuwo ehin wo, lati o gbe se aseti ati awon ohun ti o ti lo daan. Wo gbogbo iwa omugo ti o ti hu ati awon oro aifo ti o ti so; ki o si wa bere si gbadura fun ogbon rere lati fi lo ọpọ odun ti o mbo.

Bojuwo ehin wo, ki o si fi ope fun Oloran fun ibukun ti o fun o, fun ijanson imole orun ati eji ti o ti la koja, ki o si fi adura toro itosona rere, ona ibukun lodo Oluwa Olodumare, Oba Oga Ogo.

Bojuwo ehin wo ki o sora.

## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamo e wa ra ỌMỌRELA o dara pupo fun awon omode.

Ama je ki omode yi orun sun daradara o dara fun omo, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode

ỌMỌRELA BABY MIXTURE

(Ode Meji Abo 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lodo

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemists)

10, VICTORIA STREET, LAGOS.

## A NFE ASOJU

A nfe Asoju fun Ise Irohin wa Eleti-Ofe lati fi kun awon Asoju wa ni awon ilu ti a daruko si isale wonyi-

Abeokuta, Ijebu Ode, Ijebu-Igbo, Ile-Ife, Oshogbo, ati Port Harcourt.

E kowe si Olotu Iwe Irohin Eleti-Ofe, Kosoko St. Lagos.

## Waziri Ilu Boronu



Eniti a tiwe yi ni Ojoia Shetima Kashim ti o nse Oloye Waziri Ilu Boronu on pelu Alhaji Tafawa Balewa ti o nse Prime Minister lo jijo wo ile igbimo lojo Atalata. Wiwa ti o wa si igbimo yi, ko nse lati soro bikose olubanida-moran fun Ijoba ile Hausa, On si ni asoju fun awon egbe gbajumo ti o mbe nile Hausa,

## Awon Oluko Ilewe Binu Da Ise Sile

EKO, Gbogbo awon ti o nse ise Oluko nile Eko, ni abe Ijoba Federal, Ijo C.M.S. Ijo Methodist, Ijo Afrika Ijo Salvation Army Ijo Aladura, ati Baptist lo binu da ise oluko sile ti nwon si nkede kiri pe ebi npa awon lenu ise awon ko si ri owo jeun.

Ohun ti a gbo wipe o fa idi-abajo na wa ni wipe owo ososu ti nwon nfan awon Oluko nwonyi kere jojo beni gbogbo awon enia ti nwon ko ni eko iwe, lo ngba owo pirimoyan aibi ise won.


No 73/52/Vol. IX/600

## Ministry Of Lands and Labour Western Region

Applications are invited for appointment to the post of Principal Lands Officer in the Ministry of Lands and Labour, Western Region of Nigeria. The successful candidate will be in charge of the Lands Division of the Ministry.

Scale of Salary — Group 7, £2040 on pensionable terms or £2,244 on contract terms.

For further particulars and method of application, please see Western Region of Nigeria Gazette No.7 Vol. 7 Notice No. 94 of 30/1/58.

Closing date: Overseas Candidates 22/2/58

All other candidates 2/3/58

## Oro Iyanuju Si Awon Ore

"Bola ibi ma yin Oluwa nitori ore re ati nitori ise iyanu re si awa omo enia"

E de ti o se idanwo ti o si yewo nje ko ye ki eleyini yin Olorun Oba l'ogo?

Kaka ki o se be, nse ko lo lo ra akuko adie gaaku ti o gbe e lo fun Babalawo pe on lo leki on se dara-dara. Omugo po laiye.

Okunrin ti o nji faro ti o ngbe oso ti o ngbe ese ti nwon se gbe ti o gbon'fa gawu, ti o nlo si oko ti o nsise kara ti o si mbo ti o si nfi onje adidun si'nu lojojumo, nje ko ye ki eleyini se yin Oluwa l'ogo? Afi igbati "jagunlabi" gbe agbo o di ile aladura ti o ro pe tire ti on so moruo l'o nfun on ni ilera ojojumo. Eo ri okan! Ha! enyin ara mi okan mbe! ej o mbe l'orun awi-sunkun.

Ki Oba ki o fi ire kari gbogbo wa ki o si fun wa ni emi ope ati emi imore. Amin.

Yekini K. Ayilara

## E ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re




## Okunrin Kan Ku Sinu Ile Re

ILORIN. Okunrin kan ti o igjo kan die ti oruko re nje Ladipo, ara ilu Iragbeji nitosi ilu Ikirun ni a gbo wipe, o ku sinu ile re labule kan ti nwon npe ni Amoyo ni Oko Ilorin.

Okunrin kan ti nwon pe ni Olorukooba ti o je eludagbo fun Ologbe na lo so fun awon Olopa wipe okunrin na Ladipo nigbati on ri gbehin, ko si aile-ra kan lara re, iyalenu lo si je fun on nigbati on gbo wipe, o ku.

Ologbe na ti ngbe abule Amoyo to iwon odun meji. Awon olopa si nwadi gegebi oro na tito.

# Bode Nila Oyinbo



Awọn oṣiṣẹ ebute Bode gba ni a rẹwọ ninu aworan yi, awọn Onisọwọ gbe mọto wa lati wa fi ko ẹru wọn ti o de. Bi awọn oṣiṣẹ na to nko awọn ẹru na sinu mọto bẹni akọwe Onibode (Custom Officer) duro ti wọn ti nwọn nṣe iṣiro awọn ẹru ti nwọn nko lọ. Iṣẹ ṣiṣẹ bayi ko jẹki awọn Onifayawọ ri aye gbe rikiṣi wọn ṣi.

# Kilofa Ti Obinrin Fi Poju Okunrin

Olotu,

Gba mi laye lati bere lọdọ awọn ọkawe rẹ, boya ao ri awọn ọjọgbọn ati awọn amoye die ti yio le ṣe alaye ọrọ na yẹ wa. Ọrọ na, ni pataki wipe, ki lofa ti awọn ọmọkunrin fi oku pọpọ ju awọn ọmọbinrin lọ?

Ni ọdun 1921, nigbati nwọn ṣiro gbogbo awọn enia ti o mbẹ nilẹ Nigeria awọn ọjọgọn sọ wipe obinrin pọ pupọ ju ọkunrin lọ ayafi bi ọkunrin kọkan ba fẹ obinrin mẹrin mẹrin ni yio to kari awọn ọmọbinrin

Lọdun 1932 ti nwọn tun gbe iṣiro le gbogbo awọn enia ti o ngbe ilẹ Nigeria bakanna ni awọn ọmobinrin tun pọ ju ọkunrin lọ ni ipọnna merindilogun ayafi bi ọkunrin kọkan ba niyawo merindilogun ni yio to kari awọn obinrin. Bakanna ni eyiti awọn ṣe ni ọdun 1952.

Inu wa yio dun bi awọn Olotu ilera ilu ba le fi ye wa. O ha le je wipe awọn nbi ọmọbinrin pupọ ju ọmọkunrin lọ ni tabi iku lo npa ọmọkunrin pupọ ju awọn ọmọbinrin lọ ni bi?

Emi, Eni-owo Alakata

---

## E Ma Ka Iwe Iro-hin Eleti - Ofe Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re.

---


## ELECTRICITY CORPORATION OF NIGERIA

INVITATION TO TENDER

BUSH CLEARING FOR O. H. TRANSMISSION LINE IJORA — IKEJA

Tenders are invited from responsible contractors of bush clearing, tree felling and access road construction for the trace for a 132 K. V. Transmission Line from Ijora — Ikeja.

The distance of approximately 9 miles will be divided into two sections and contractors may tender for one or both sections.

Tender documents may be obtained on payment of a deposit of £5. 0. 0d. from.

The Secretary,
Electricity Corporation of Nigeria
Headquarters,
Private Mail Bag 1001
Ijora, EBUTE METTA.

Tenders enclosed in sealed envelopes endorsed "TENDER FOR BUSH CLEARING - IJORA IKEJA" must be received at the office of the Secretary not later than 12 noon on the 22nd February, 1958.

Upon receipt of a Bona Fide Tender the tender deposit of £5. 0. 0d. will be refunded.

The Electricity Corporation does not undertake to accept the lowest or any tender.

Further information concerning the contract may be obtained on application to the Chief Electrical Engineer at this Headquarters.

ARTHUR PAUL
SECRETARY

Electricity Corporation of Nigeria,
Headquarters,
Ijora, Ebute Metta.
31st January, 1958.



Bi Iwo Ba Fe Je'Gbadun

Ra Siga BICYCLE

Ti O L'okiki Nile Nigeria



# Alapara Ibadan Nki Yin o

Oke Foko
Ibadan

Boya ero apara mi ose yi le fo kan e. Pese, kio mu kan e ni idodo, Awe lowo, e ma binu. Alapara Ibadan ko nse ore enikan Alapara Ibadan is for anybody. Oyinbo ni mo mo ni sio yen. Oyinbo. Yu kolu mi yu kolu gbegiri ati amala pelu opolopo eran ni opopo oja Gege. Oyinbo Oke Foko ni mo mo nfo yen o.

Oyinbo ti de ilu Ibadan ojo ti pe ni gere ti nwon kuro ni Abeokuta ilu Egba. Se enyin ara mi na wa ri wipe a ti nba won se Akiriyo tipe.

KIRIYO KO NSE ILU

Kiriyo tabi Onibuku tabi Onigbagbo ni e tile npe won ti de odo wa nih-hin le ojo kan ni. O bere lori awon baba wa Olayele ti o fi omo re fun awon Oyinbo ni Kudeti wipe ki won ba on ko won ni ogbon Ogbon oselu koo-ogbon bi a tise akiriyo ni A ni bi a ti nse akiriyo awa yio ni ti atata.

Awe, inu mi dun nigbati awon Onigbagbo patakipataki fi iwe pe mi si ajo pataki ni Kudeti wipe awon yio soro pataki si eti gbo awa ogberi. Nigbati mo nlo mo gbe Bibeli lowo tabi Buku le npe? oro pataki dun gbo, awe a ni ti o ba tile jade ninu Majemu atijo ti ko nse Majemu asiko yi. Awon Onigbagbo pataki se ipinnu wipe ko ye ki Alufa Olorun ma se soboleaan si nkan ile aiye ile asan. Won ni oro a mba won se jiu awon ko gbodo gbo lodo Alufa orise Olorun kan mo.

Mo joko m o ya enu, awo ito ko lenu mi o wa mu mi nimn wipe awon Alufa Akiriyo ti se ipinnu nigbati won nfi won je oye ijo wipe awon yio ko ehin si nkan aiye. Emi Alapara Ibadan ti gba Kola kehin-saiye. Mo ni oye ko-ehin-saiye. E ba mi ka Buku (bi awon Kiriyo atijo ti npe iwe Bibeli aiyeo o) Woli Danieli ko nse eala Dani-dani o. oju iwe Daniel ori keji, ese k'erin o le ni ogoji.

E ba mi ka "Li ojo awon oba wonyi ni Olorun orun yio gbe ijoba kan kale, eyiti a ki yio le parun titi lai"-a ni titi lailai. Akiriyo ko nse kapeni Mo juba ore mi Adelabu ati Ogbeni Olopoenia. Oro Alufa Alapara Ibadan ni e gbo yen o. Mo ti siwo ninu a nba yin soro eto ilu o.

OWO ORI OWO ILE ERO

Awe, ti mo ba tile siwo ninu a mba won da si oro eto ilu nko gbodo ma san owo ori. Jesu ni ki san Awolowo ni ki san Adelabu ni ki nbo si kosa ki nyewo bi o ba ti fiti mi ki nsan Boya oro Wowo o fiti re ko de Ebute Irele ni Okitipupa nibiti a ko nsan owo ori.

Bi ko ba si ajeara a ti odu Ifa masan-owo-ori ti mo sa bayi ni "Iganse meta a fo aifaraba lo da fun giripa okunrin ti o ni on ko ni san owo ori, ti a wi fun titi ti o ni on ko ni gbo a fi bi awon olope ko ba de" Odu Ifa yi dara pupo bi esia ba moki, sugbon inawo ebo re po pupo.

Orisa aladimu re ni wipe wa lo si Oke Mapo tabi ni Ake ni Abeokuta tabi ni Ebute Irele ni Okitipupa wa lo san oke metala bi o ba ni oko koko tabi baba onirobe wa san ogbon oke aile tabi owo ori Onipo.

Eleyi ko nse owo apo Alufa Alapara ko nse ti Awolowo beni ko nse ti Sardauna ni Kaduna tabi Azikiwe ni Enugun. Owo Anfani ti a ari ni ilu ni o.

SUNGBO, OLOWO AIYE

Ta ni o wipe Sugbon ko bi omo? Alapara niran omo ti Sungbo Olowo aiye bi ni o nje oba ni ilu Itopia (Ethiopia ni Abisinia) titi di oni ojo rere.

# Awon Scout Ile Nigeria



Awon ti a nwo ninu aworan yi ni awon Scout ile Nigeria ti o ba won lo ye ayo ainjua Jamboree ailu Oyinbo lodun to koja.

Alaiyelewa oba ilu Gesi ni a nwo ti o ngba owo lowo awon Scout na. Ogbeni Alagba Sir Boden Powell ti o nse olori fun gbogbo awon Scout agbaiye ni a nwo ti o duro lana won.

In gayama gayama In fulu.
Yabo, yabo In fubu.

---

# A NFE ASOJU

A nfe Asoju fun Iwe Irohin wa Eleti-Ofe lati fi gun awon Asoju wa ni awon ilu ti a daruko si isale wonyi:-

Abeokuta, Ijebu-Ode, Ijebu-Igbo, Ile-Ife, Oshogbo, ati Port Harcourt.

E kowe si Olotu Iwe Irohin Eleti-Ofe, Kosoko St, Lagos.

---



## Olopa Fe S'igun Si Awon Isansa Ni Ibadan

IBADAN. Awon Olopa ilu Ibadan ti sekeri wipe bi awon olomo fa omo won lele, nitoripe gbogbo awon isansa alairise kan se ati awon omo gagan ati awon omo Ojuko, ti awon origba ewaiye kaakiri ni oja Dugbe Mokola Gege Amunigun Agbeni Gbagi ati ni Oja'ba tabi awon ti ko ni oja ra ti awon nwo sohu kiri enikeni ti awon ba ri ti o nse bo, Olopa yio mu won,

Awon olopa so wipe lehin ti awon ti gbogun ti won ni Eko awon odelesinrin na tun osa si Ibadan.

Nigbati awon ba bere si ko awon enia na awon obinrin ti o ba wa larin won kiko ni pelu.

JOY OF LIFE
VITAL ENERGY and YOUTH
are preserved through
**DYNAMIREN**
according to
DR. LABOSCHIN of
BERLIN/GERMANY
The only activated
hormone preparation
that gives
HERCULEAN STRENGTH
and BEAUTY
Also
Combats Nervousness
and Promotes Appetite
Price 12/6d
Sole Agents :-
WATERLOO MEDICINE
STORES
8 Palm Church Street
P. O. Box 333
Lagos, Nigeria.
Phone 22878

## Iwadi Ore Bere Nilu Ilorin

ILORIN. Awon Oluwadi bere iwadi lojo Jimo ana, bawo ni Ilorin tise je ti Yoruba.

Nina awon enia ti yio soro nibe ni Alaiyeluwa Oni Ife, nitoripe on ni Oba ile Ife gbogbo itan Yoruba owe lati ile Ife ni awon ti sun jade, enu re ni itan si sojo si.

A gbo wipe iye awon ti yio soro ko din ni adota. Oloye Rotimi Williams ni yio se agbejoro fun won. Olofa ilu Offa papaa ati die ninu awon Oba Ekiti yio fi itan bale.

Sehu Abudu Kadiri, Oba Ilorin yio pitan bawo ni on ti se je Fulani. Ojo meta pere ni awon Oluwadi na yio se ni Ilorin. awon enia ti yio soro, ti o si mo itan daradara ti bere si wo ilu.

A tun gbo wipe ni bi ijoko igbimo na Oluwadi oro na ko ni fe enia pupo tayo ogorun simu ile ti awon fe joko nitoripe ko si aye pupo oru yio si mu pupoju.

## Akiyesi Pataki

A fi eyi kede fun gbogbo enyin Asoju Iwe Iroyin wa nile Yoruba, l'oke Oya, nile Ibo, l'oke Okun ati nilu Oyinbo wipe enikeni ti ko ba fi owo wa ranse ki osu to pari so ko oruko re fun Loya Eleti-Ofe, so ba se ejo so si gba owo irin ese lowo re.

OLOTU.

**HMV RED LABEL**

Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS



Read the latest popular titles

JZK 1000 - Bowo Fun Oluwa/Owo Niyi Omo Laso
" 1001 - Iseku Oluwa Ko/Baba Kari Wa Olote Grawo Baptist Church Choristers Yaba.
" 1002 - Yodeni Ajanbi/Oyugbo Yoneyin
" 1003 - Miss Jerutude Pon/Mikan Fadi
" 1004 - Atono Nado Na Woyi/Alo Nado Towe Dranvendgo Amandekpo & His (Jegbera) Band
" 1005 - Metua Laafe/Yoyo Lona Atsiye
" 1006 - Oluse/Aiyeo Oba Ilu Oyinbo S.O.A. Ladipo & His (Koranic) Group.

" 1007 - Aka-Ofiodo/Memuna Lenboye
" 1008 - Owo Tegbatewe/Wahi Asimolowo
" 1009 - Ilori/Ologbon Aiye Kelani Yesufu & His (Sakara) Band.
" 1010 - Igbomina/Tafa Sawo
" 1011 - Waka Odolaiye/Babatunde Omo
" 1012 - Sonmoori Yeye/Ewi Odolaiye Odolaiye Aremu & His (Pankeke) Band.



OBTAINABLE FROM :-

1. Y.A. Sikoanmi-87, Victoria Street, Lagos
2. Asimawun Stores-24 " " "
3. Salawu Aremu-73, " " "

Sold by all the best stores

"HIS MASTER'S VOICE" Yellow Label RECORDS

THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street P.O. Box 647 Lagos Phone 23330